*Iree rẹ̀ ku ọjọ́ méje lónìl*
*Ti wọ́n ó sílẹ̀kùn iré fún ọ*
*Gbogbo iré ní ó tòó ọ lọ́wọ́*
*Ṣùgbọ́n gbogbo ẹbọ rẹ ni kóo rú o*
*Ọlọ́fin bá rúbọ ẹ̀ nígba nígba*
*Nígbà ti àwọn Babaláwo ri bí ẹbọ́ ti pọ̀ tó*
*Ẹ̀rú bá ń ba Yangí aborí kugú*
*Ojora mú Yàngìdì Awo ẹsẹ̀ òkè*
*Èrú sìn ba Ẹ̀rín gbàdàgì Awo Aláṣẹ*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ̀ nìkan ló ní e jẹ́ káwọn ó tèlè n tÍfá wí*
*'Ifá è é wí kinní kan kó mọ́ ṣẹ̀'*
*'Ẹni ti ó bàá sọmọ Ifá ó mọ́ọ tẹ̀lé ìlàna ẹ̀'*
*'Pé n tÍfá wí máà nù u'*
*'Yóó sò mọ́ọ ṣẹ bÍfá ti wí un náà lọ'*
*'Yóó sì mọ́ọ forí tì'I'*
*'Téèyán bá forí tì'I'*

*‘Olúwa ẹ̀ níí là’*
*Wón ń ṣẹ́ bẹ́ẹ̀kẹ́ bọ̀*
*Ńgbà wọ́n rúbọ tán*
*Ọlọ́fin ní ‘èyin Babaláwo yìí’*
*‘Iré lẹ́ ní ń bò ńjọ́ méje yìí o’*
*‘Ẹbọ lẹ́ sì yàn’*
*‘Lòún rú nígba nígba o’*
*‘Iré ọ̀hún ò gbọdọ̀ mó dèé o’*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ́ níree rẹ́ ó dèé*
*‘Ńgbà o ti rúbọ tó pé’*
*Ọlọ́fin ní sùgbọ́n ẹ́ mọ́ọ wá ńjoojúmọ́ tíjọ́ méje é e pé ni*
*Tóun ò bá fi ríre náà*
*Gbogboo yín lòón ó dàá loro*
*Wọ́n ń lọ*
*Wọ́n ń bọ̀*
*Ngbà ó dijó kẹ́ta*
*Yangí aborí kugú*
*Òun kọ̀*
*Kò lọ mọ́*
*Ó ní ńgbà tí kinní yìí ò bá ní rí bẹ́ẹ̀ mọ́*
*Kénìkan ó mọ́ lọ̀ọ́ han òun léèmọ̀*
*Ọ́ jókòó ńlé ẹ̀*
*Ńgbà ó dijọ́ kẹ́rin’*
*Yàngìdì Awo èṣè,òkè náà kò,*
*Òun náà lóun ò lọ mọ́*
*Ó ní ńgbà ti ó bàá dìgbà náà*
*Ti nnkan ọ̀hún ò bà ní ṣeè ṣe mọ́*
*Ẹ̀rín gbàdàgì Awo Aláṣẹ ńtiẹ̀*
*Ńgbà ó dijọ́ karùún*
*Òun náà ò lọ mọ́*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ́ pé ẹ́ jáwọ́n ó mọ́ọ lọ*
*‘E bí n tÍfá wí làwọ́n wí’*
*‘Ifá ló pé iree rè ku ọjọ́ méje’*
*‘Tó sì níre náà ó wàá bá a’*
*Tó sì ní káwọ́n ó rú ohun gobgbo ní mùre mùre*
*Ẹ́ jáwọ́n ó mọ́ọ lọ*
*Ngbá ó dijó kẹ́fà*
*Akòko ni dèùrè nìkan ló lọ Ilé Ọlọ́fin*
*Ijó keje pé*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ̀ ló tún dá lọ ilé Ọlọ́fin*
*Iré bá dé*
*Òpìtìpìtì iré ni ọ́n rù dé fún  Ọlọ́fin*
*Ẹṣin ni*
*Ọlà ni*
*Aṣọ ni*
*Iré gbogbo nìí*
*Iré yìí pọ̀!*

*Ọlọ́fin ní kí wọ́n mọ́ọ pín in*
*Ó ni Yangí aborí kugú dà?*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ́ lóun ò ri ko wá mọ́*
*Yàngìdì Awo ẹsẹ̀ òkè nkọ́ńtiè?*
*Ó lóun ò rí òun náà kó wá mọ́*
*Ẹ̀rín gbàdàgì Awo Aláṣẹ dà?*
*Òun náà ò wá mọ́*
*Ọlọ́fin ló dáa*
*Ó ní gbogbo ọlá tó tọ́ si wọn*
*Mọ́ọ bó gbogbo ẹ̀ lọ*
*Wọ́n bá kó gbogbo ẹ̀ lé Akòko ni dẹ̀ùrẹ̀ lọ́wọ́*
*Ńgbà Akóko ni dẹ̀ùrẹ́ ń padà relé ẹ̀*
*Ó bá ya ilée Yangí aborí kugú*
*Ó wèyin è ló rọ́kọ̀*
*Ló rí gbogbo ihun ti ọ́n kó fún un*
*Ó lóun ò pé ẹ jẹ́ á forí tìí?*
*Kò pé tiẹ̀ ni mọ́*
*Ó ní ihun ti ọ́n fún òun nùu*
*Ó ya ojúde Yàngìdì Awo ẹṣẹ̀ òkè*
*Òun náà jáde*
*Ló rí ẹ̀rù ńlẹ̀*
*Àṣé báyìí ní ó rìí?*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ̀ lóun ò pé ẹ jẹ́ a forí tìí?*
*Ó délé Ẹ̀rín gbàdàgì Awo Aláṣẹ*
*Ó ké sóun náà*
*Òun náà ní hàáà*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ̀ lóun ò pé ẹ jẹ́ á ní sùúrù*
*Akóko ni dẹ̀ùrẹ́ bá kó gbogbo ọlà relé ẹ̀*
*Kò pé tiwọn lèyí*
*N ní wá ń jó ní wá ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Yangí aborí kugú*
*Yàngìdì awo ẹ̀sẹ̀ òkè*
*Ẹ̀rìn gbàdàgì awo Aláṣẹ*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ̀ níí ṣe ọmọ ikẹ́yìin wọn lénjé lénjé*
*Àwọn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin lỌlọ́fin pè nÍfá*
*Yangí aborí kugú*
*Ẹ̀  bá jẹ́ a forí tìí fún Ikin*
*Yàngìdì Awo ẹṣẹ̀ òkè*
*Ẹ̀ è bá jẹ́ á forí tìí fún Ikin*
*Ẹ̀rín gbàdàgì Awo Aláṣẹ*
*Ẹ̀yin ò kúkú forí tìí dópin*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ̀*
*N ló wáá forí tìí fún Ikin*
*Ẹ̀ní bá forí tìí*

*NImọlẹ́ ó gbè*
*Akòko ni dẹ̀ùrẹ́*
*Awo rere mọ̀mọ̀ ni*

***Òtúá Ọ̀kànràn A***
*Ifá le pide a esta persona que ofrezca perseverancia como sacrificio. Esto es lo que le traería riqueza. Cuatro personas incluso esta persona harían un negocio. Ellos deben soportar (aguantar, resistir) para que no resulte que uno de ellos se lleve las ganancias de todos ellos.*

*Yangí aborí kugú*
*Yàngìdì Awo seè òkè*
*Èrín gbàdàgì Awo Aláse*
*Akòko ni dèùrè es el último de ellos*
*Los cuatro eran los sacerdotes que Olófin llamó a adivinación de Ifá*
*Que ellos deben lanzar adivinación para él usar Ìbò*
*Usted Olófin, ellos dijeron*
*Sus fortunas buenas habrían entrar en tiempo de siete días*
*Precisamente en siete días, ellos abrirían la puerta de fortuna para usted*
*' Todo las fortunas lo conseguirían ', ellos predijeron*
*' Pero usted debe ofrecer todo el sacrificio prescrito por completo '*
*Olófin ofreció el sacrificio por completo*
*En ver la temeridad con la que  él lo ofreció*
*Yangí aborí kugú empezo a desarrollar pies fríos*
*Igualmente Yàngìdì Awo esè òkè*
*El miedo también agarro Èrín gbàdàgì Awo aláse en sus obras*
*Pero Akòko ni dèùrè postulo ' Permítanos seguir las postulaciones de Ifá '*
*' Ifá nunca dirá algo y no vendría a pasar '*
*' Quienquiera que va a ser un niño de Ifá seguiría sus pasos '*
*' Que, ésas eran las predicciones de Ifá '*
*' Él actuaría entonces en la semejanza de la predicción de Ifá '*
*' Él también perseveraría '*
*' La persona que perseveran '*
*' Es esa persona que se haría rica finalmente '*
*Debido a Akòko ni dèùrè está proponiendo, ellos continuaron*
*Inmediatamente después de todos los sacrificios habían sido completados*
*Olófin amenazó ' la fortuna que usted dijo a viniendo no debe estar por otra parte '*
*' Usted ha predicho que mi fortuna llegaría a siete días '*
*' Y usted ha prescrito sus sacrificios '*
*' Yo lo he ofrecido en múltiplo de centenares '*
*' Las fortunas no deben dejar de venir '*
*Tranquilizantemente, Akòko ni dèùré dijo ' sus fortunas buenas vendrían '*
*' Desde que usted ha observado el sacrificio por completo '*
*' Pero usted debe informar todos los días a mí para la duración de los siete días ' Olófin dijo*
*' Si yo no pudiera ver la fortuna buena '*
*' Yo le mostraría el infierno a todos ', Olófin amenazó*

*Ellos estaban informando diariamente*
*Ellos dejarían para sus casas respectivas por la tarde*
*En el tercer día*
*Yangí aborí kugú en su propio*
*Él se negó*
*Él no fue de nuevo*
*' Si en caso de que estas predicciones no demuestran verdad '*
*' Con tal que nadie me vería en el infierno '*
*Él dice abajo en su casa*
*En el cuarto día*
*Yàngìdì Awo èsè òkè también se negó*
*Él no fue de nuevo*
*' Cuando el tiempo viene '*
*' Y resultaría ser lo opuesto de nuestra predicción '*
*Èrín gbàdàgì que nota la ausencia de sus dos amigos*
*Él tomó una decisión final en el quinto día*
*Él también se negó a informar*
*Akòko di dèùré ánimo que ellos continuaran de nuevo*
*' Lo que no es Ifá, predijo que nosotros pronunciamos '? Él dijo*
*' Es Ifá que predijo que las fortunas buenas de Olófin entrarían en siete días '*
*Y Ifá dijo categóricamente que las fortunas vendrán a él*
*Es el mismo Ifá que nos había dicho que realizáramos el sacrificio generosamente*
*Permítanos continuar yendo*
*En el sexto día*
*Akòko ni dèùrè solo informó en la casa de Olófin*
*En el séptimo día también*
*Era como de costumbre Akòko ni dèùrè solo como usualmente fue a la casa de Olófin*
*La fortuna buena sin el aviso llegó*
*Incuantificable suma de fortuna buena vino para Olófin*
*Caballos*
*Propiedades de valor inmensurables*
*Telas*
*Todas las fortunas buenas*
*El cúmulo es impresionante*
*Olófin pidió a sus sirvientes inmediatamente al divino*
*¿Dónde está el Yangí aborí kugú? Olófin preguntó*
*' Yo no puedo verlo ' contestó Akòko ni dèùrè*
*¿' Que sobre Yàngìdì Awo esè òkè '?*
*' Él se negó a venir de nuevo ' Akòko dijo de nuevo*
*¿' Èrín Gbàdàgì Awo Olófin '?*
*' Yo tampoco puedo verlo ' Akòko concluyó*
*' Eso está bien ', Olófin dijo*
*' Todas las propiedades que son debido a tres de ellos '*
*' Usted Akòko ni dèùrè deben ir con ello '*
*Eso era cómo ellos condensaron la propiedad de cuatro personas para él solo*
*Cuando Akòko ni dèùrè estaba devolviendo casa*
*Él detuvo por la casa de Yangí aborí kugú*

*Yangí aborí kugú miro en asombro, el sendero de fortunas en carretas de caballo,*
*' Todos éstos para usted solo ', él preguntó, petrificado*
*' No dije yo que usted persevera '? Akòko ni dèùrè dijo*
*Él no dijo que la porción de Yangí aborí kugú se concluye*
*' Ésta es mi porción ', él dijo*
*Él detuvo por la casa de Yàngìdì awo ese òkè*
*Él tambien salio apresurado*
*Él vio el montón de bienes*
*' Así que esto es cómo habría de volver '? Yàngìdì dijo*
*' No hizo yo le dije, todo para ser paciente ' Akòko ni dùùrè dijo repetidamente*
*Akòko ni dùùrè tom toda los regalos a casa*
*Él no dijo ninguna fortunas corresponde a ellos*
*Él empezó a bailar y regocijar entonces*
*Él estaba alabando su Babaláwo*
*Su Babaláwo estaba alabando Ifá*
*Él dijo que era exactamente como su Babaláwo había dicho*
*Yangí aborí kugú*
*Yàngìdì Awo esè òkè*
*Èrín gbàdàgì Awo Aláse*
*Akòko ni dùùrè es el último de todos*
*Los cuatro eran los sacerdotes que Olófin llamados a adivinación de Ifá*
*Yangí aborí kugú*
*Usted debe preferir permítanos perseverar para Ikin*
*Yàngìdì Awo esè òkè*
*Usted debe preferir permítanos perseverar para Ikin*
*Èrín gbàdàgì Awo Aláse*
*Usted debe preferir permítanos perseverar para Ikin*
*Akòko ni dùùrè*
*Es el que había perseverado para acabar*
*Quienquiera persevera al final*
*Es la persona que las Deidades tomarían partido con el*
*Akòko ni dùùrè*
*Usted es un sacerdote real*

***Òtúá Ọ̀kànràn B***
*Ifá pé òun pé òun ó eléyìun lé gbogbo Ajogun lọ. Ẹbọ ni ká rú torí iré kan ti ń bọ̀ wá inú ilée wa. Ifá pé ká rọ́jú ra iré ọ̀hún torí iré ọ̀hún ní ó lèé ikú ọ, yóó lèé àrùn ọ ati gbogbo Ajogún. Ifá pé kí eléyìun ó mọ́ọ sin ajá.*

*Ẹtú ń be nígbó*
*Etú ń jewée gbégbé*
*Èkìrì ń bẹ lọ́dàn*
*Ń be jèèso Àlọ̀*
*Àgbọ̀nyín igbórò*
*Ń bẹ nínúu sàànsáàn tí ń jẹ òlasa ọde*
*A díá fún Ọ̀rúnmìlà*
*N lo rèé rOjúlawò lẹ́rú*

*Ọ̀rúnmìlà ló rẹ́rú rẹ́rú*
*Ló wáá ra ẹ́rú kan yìí*
*Ló bá sọ ọ́ ní Ojúlawò*
*Ojúlawò àti Ọ̀rúnmìlà bá ń ṣe Ilé ayé lọ*
*Wọ́n jọ́ ń bẹ*
*Ńgbà ó dijọ́ kan*
*Ojúlawò bá di ajá!*
*Ajogun ikú tó bá póun ń bọ̀ wáá bá Ọ̀rúnmìlà*
*Ojúlawò ń bá a lé e lọ*
*Àrùn*
*Ń lé e lọ*
*Ọ̀fò*
*Ń lé e lọ*
*LỌ̀rúnmìlà bá ń jí ní ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Etú ń bẹ nígbó*
*Etú ń jewée gbégbé*
*Èkìrì ń bẹ lọ́dàn*
*Ń jèèso Àlọ̀*
*Àgbọ̀yín igbórò*
*Ń bẹ nínúu sàànsáàn tí ń jẹ ìlasa ọdẹ*
*Ạ díá fún Ọ̀rúnmìlà*
*Ṇ́ lọ rèé rOjúlawò lẹ́rú*
*Ṇ́ wá n lékúú lọ́ ò*
*Ṇ́ lárùún lọ*
*Ń lófòó lọ*
*Òkìràkìrà*
*Ẹ́ wá wOjúlawò ti ń lékúú lọ*
*Òkìràkìrà.*

***Òtúá Ọ̀kànràn B***
*Ifá desea bien a esta persona. Ifá dice que él ahuyentaría todos los Ajoguns lejos para él. Ifá le piden que ofrezca sacrificio debido a una cierta fortuna buena que está viniendo a él. Él se exhorta que se esfuerza por comprar la fortuna porque es la fortuna que ahuyentaría la muerte lejos. Él se manda para criar perros como animales domésticos.*

*Etu está en el bosque*
*Etu está comiendo las hojas de árbol de Gbégbé*
*Ekìrì está en la sabana*
*Está comiendo las semillas de Àlò*
*El bosque limitó al antílope*
*Está en los céspedes altos que comen las hojas de okra plantados por el cazador*
*Adivinación lanzada para Òrúnmìlà*
*Él iba comprar Ojúlawò como un esclavo*

*Es Òrúnmìlà que había comprado a tantos esclavos*
*Pero en comprar este en particular*
*Él lo nombró Ojúlawò*
*Los dos de ellos continuaron en armonía*
*Ellos viven juntos*
*Un día fatal*
*¡Ojúlawò se volvió un perro!*
*Todos los hechizos de muerte que vinieron hacia Òrúnmìlà*
*Ojúlawò los cazó lejos*
*Enfermedades*
*Él los cazó lejos*
*Pérdidas*
*Él los cazó lejos*
*Òrúnmìlà empezo a bailar y regocijar entonces*
*Él estaba alabando su Babaláwo*
*Sus Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Él dijo que era exactamente como su Babaláwos dijo*
*Etu está en el bosque*
*Etu está comiendo las hojas de Gbégbé*
*Ekìrì está en la sabana*
*Está comiendo las semillas de Àlò*
*El bosque limitó al antílope*
*Está en los céspedes altos que comen hojas de okra del cazador*
*Adivinación lanzada para Òrúnmìlà*
*Él iba compra a Ojúlawò como un esclavo*
*Él ahuyenta ahora la muerte lejos*
*Él realmente ahuyenta lejos enfermedad*
*Él caza lejos la Pérdida*
*Òkìràkìrà*
*Venga y vea Ojúlawò que ahuyenta la muerte lejos*
*Òkìràkìrà*

***Òtúá Ògúndá A***
*Ifá pé kí eléyín ó rúbọ kí wọ́n ó mọ́ọ fi nǹkan yìn ín lọ́wọ́*

*A yín yin*
*A yìn yin*
*A yìn yìn ǹ yin yìn*
*Awo ilé Òrúnmìlà*
*Àwọn ló díá fún Òrúnmìlà*
*Níjọ́ tIfá ń ṣehun ẹyìín kárí ayé*
*Wọ́n níwọ Òrúnmìlà*
*Ìwọ ni o lọ́ọ́ mọ́ọ tún ilé ayé ṣe*
*Òrúnmìlà ṣe bẹ́ẹ̀*
*Ní ń wọ Olókùrùún yè*
*Ní ń jáwé*
*Ní ń wa egbò*

*Ni nnkán n yìn ín lọ́wọ́*
*Ẹni ti ò rọ́mọ bí ń bímọ*
*Ágàn ń tọwọ́ ààlà bosùn*
*Aboyún ilé ń bí tibi tire*
*Ení ó bí*
*Wọn ò kú*
*Wọ́n ń yin Ọ̀rúnmìlà*
*Ọ̀rúnmìlà ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*A yín yin*
*A yìn yin*
*A yìn yìn ǹ yin yìn*
*Awo ilé Ọ̀rúnmìlà*
*Àwọn ló díá fún Ọ̀rúnmìlà*
*Níjó ítIfá ń ṣehun ẹyìín kárí ayé*
*Àyìnkàn*
*Àyìnkàn láà yÀyin*
*Ẹnu tẹ́ẹ́ bá mu yin Ẹ̀dú*
*Ẹ mọ̀mọ́ pa á dá*
*Àyìnkàn*
*Àyìnkàn làá yin àyin*
*Mọ̀ránhin mọranhin làá wíràn oyin*
*Ẹnu tẹ́ẹ́ mú yin Ẹ̀dú*
*Ẹ mọ́mọ̀ pa á dà*
*Mọ̀ránhìn mọranhin làá wiràn oyin*
*Àwídùn mọ́mọ́ làá wíràn iyọ̀*

***Òtúá Ògúndá A***
*Ifá desea bien a esta persona. Él se manda para realizar sacrificio para las personas alabarlo (elogiarlo) para sus hechos buenos.*

*A yín yin*
*A yìn yin*
*A yìn yìn `n yin yìn*
*El sacerdote de la casa de Òrúnmìlà*
*Ellos son unos que lanzaron adivinación para el Òrúnmìlà,*
*En el día que Ifá estaba realizando cosas de alabanza alrededor del mundo*
*Usted Òrúnmìlà, ellos dijeron*
*Usted debe ir y debe remendar (ir mejorando) el mundo entero*
*Òrúnmìlà hizo como dijo*
*Él estaba alimentando al enfermizo con éxito*
*Él estaba cosechando hojas de los bosques para la medicina*
*Él estaba desarraigando las raíces*
*Él se alabó (ensalzar) para los actos*
*Aquéllos que no tenían ningún niño entregaron bebés*

*La esteril se puso embarazada*
*El embarazo se entregó a ambos bebé y placenta*
*Aquéllos que ya tenían bebés*
*Los bebés no se murieron*
*Ellos estaban alabando a Òrúnmìlà*
*Òrúnmìlà estaba alabando su Babaláwo*
*Los Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Él dijo que que era exactamente como sus Babaláwos había dicho*
*A yín yin*
*A yìn yin*
*A yìn yìn `n yin yìn*
*El sacerdote de la casa de Òrúnmìlà*
*Ellos fueron que lanzaron adivinación para Òrúnmìlà*
*En el día que Ifá estaba realizando cosas de alabanza alrededor del mundo*
*Está listo con alabar*
*Está listo con alabar que uno debe alabar Àyin*
*La boca que usted usa alabando Èdú*
*No lo cambie*
*Listo para Alabar*
*Está listo con alabar que uno debe alabar Àyin*
*Con dulzura, uno narraría el sabor de miel*
*La boca que usted usa alabando Èdú*
*Por favor no lo cambie*
*Con dulzura, uno narraría el sabor de miel*
*Con simpatía (amabilidad), uno diría sobre la experiencia del sabor de sal.*

***Òtúá Ògúndá B***
*Ifá lóun ò níí jẹ́ kí Ajogun ó mú eléyiun.*

*Òtúá re irá*
*Bẹ́ẹ̀ ni ò dé Irá*
*Àkòkì ló ràjò*
*Bẹ́ẹ̀ ni ò bọ̀ àjò*
*Òótọ́ inú lájẹkù ó ju irọ́ lọ*
*A díá fún Ìràwọ̀ sàásà*
*Èyín ti ń gbóguún rẹ̀bá ọrún*
*Wọ́n ní kó rúbọ*
*Kó lè baà sé ìlẹ̀kùn ogun mọ́ ọrún*
*Ogun kan ò lè dọ́run*
*Ìràwọ̀ ò níí jẹ́*
*Bógun bá ń bọ̀*
*Ìràwọ̀ ní ó tan iná mọ́ ọ*
*Ní ó jàá sòòrò*
*Ogun kan tó le mú ọrún ò sí*
*Ayé yẹ Ìràwọ̀ sàásà*
*N ní wá  ń jó ní wá ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*

*Àwọn Babaláwo n yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Òtúá re irá*
*Bẹ́ẹ̀ ni ò dé Irá*
*Àkòkì ló ràjò*
*Bẹ́ẹ̀ ni ò bọ̀ àjò*
*Òótọ́ inú lájẹkù ó ju iró lọ*
*A díá fún Ìràwọ̀ sààsà*
*Èyí ti  ń gbóguún rẹ̀bá ọ̀rún*
*Ẹ mọ jógun ó jà mí*
*Ẹ mọ́ jógun ó jọ̀ruùn mi*
*Ìràwọ̀ sààsà*
*Ogun ò gbọ̀dọ̀ jòde ọ̀rún*
*Ìràwọ̀ sààsà*
*Ifá mọ́ jógun ó jà mí dákun*
*Ìràwò sààsà.*

***Òtúá Ògúndá  B***
*Ifá dice que él no le permitirá a esta persona ser arrestado por cualquier Ajogun.*

*Òtúá salio para Irá*
*Todavía no llega a Irá*
*Àkòkì siguió un tropiezo de viaje*
*Todavía no vuelva del viaje*
*La verdad en uno tiene un sobrante que es más grande que la falsedad*
*Adivinación lanzada para Ìràwò sààsà*
*El que estaba emprendiendo guerra cerca de los cielos*
*Le pidieron que realizara sacrificio*
*Tal que él cerraría la puerta firmemente contra guerras que vienen al cielo*
*Ninguna guerra puede alcanzar los cielos*
*La estrella nunca lo permitiría*
*Siempre que cualquier guerra esté viniendo*
*La estrella habría tener un brillo*
*Y golpearía como el meteoro*
*Alli no es guerra que alcanzaría los cielos*
*Vida  tan contento de Ìràwò sààsà*
*Él empezó a bailar y regocijar entonces*
*Él estaba alabando su Babaláwos*
*Sus Babaláwos estaban alabando Ifá*
*Él dijo que era exactamente como su Babaláwos había dicho*
*Òtúá salio para Irá*
*Todavía no llega a Irá*
*Àkìkì siguio un tropieso de viaje*
*Todavía no vuelva del viaje*
*La verdad en uno tiene un sobrante que es más grande que la falsedad*
*Adivinación lanzada para Ìràwò sààsà*
*El que estaba emprendiendo guerra cerca de los cielos*

*No me permita saber guerra*
*Nunca permita el cielo, mi guerra de experiencia de lugar de descansando,*
*Ìràwò sààsà*
*La guerra nunca debe consumir los cielos*
*Ìràwò sààsà*
*Ifá, nunca me permite experimentar guerra*
*Ìràwò sààsà.*

***Òtúá Ọ̀sá A***
*Ifá pé a ò gbọdọ̀ yẹ àdéhùn o. Àwọn méjì Kí nÍfá rí tójú ọmọ́ ń pọ́n. Kí àwọn mèjèèjí ó wáá rúbo ndíí Ifá òhún kí wón ó ṣì fi eku méjì pèsè fún àwon ayẹ lóríta, àwon méjèèjì ní ó jo bímọ.*
*Kọ̀ kọ̀ kọ́rọ́nyín*
*Awo adìẹ lố díá fún Adìẹ*
*Níjó tí Adìẹ ń fomi ojúú sògbérè ọmọ*
*Wọ́n ní yóó bímọ lọ́pọ̀lọpọ̀*
*Ẹbọ ọmọ ni kóó wáá ṣe*
*Kọ̀ kọ̀ kọ́rọ́nyín*
*Awo Àwòdì ló díá fún Àwòdì*
*Àwòdì náà ń fomi ojú sògbérè ọmo*
*Wọn ní yóó bímọ lọ́pọ̀lọpọ̀*
*Ẹbọ ọmọ ni kó wáá ṣe*
*Àwọn méjèèjì ni ọ́n jọ lọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmìlà*
*Àwọ́n le bimọ báyìí?*
*Ọ̀rúnmìlà lẹ́ẹ́ bìímọ*
*Ó ní kí wọ́n ó lọ̀ọ́ rú ẹmọ mẹ́wàá*
*Wọ́n ní kí wọ́n ó sì rú ọ̀pọ̀lọpọ̀ owó lọ́nà mẹ́wàá*
*Ó ní wọ́n ó bìómọ pupọ láyé*
*Wọ́n bá padà lọ ilé*
*Adìẹ́ wá ẹmọ́ lọ*
*Ó rí méjì péré*
*Ó kó méjì ọ̀hún sílẹ̀*
*Ńgbá tí Awòdì ó kòó tiẹ dé*
*Ó rí mẹ́jọ*
*LAdìẹ bá ń ronú pé ẹbọ àwọn ò gbọdọ̀ kọjá òní*
*Tí baba yìí ní kí àwọ́n kó ẹbọ wá*
*Ẹmọ́ sì lòún wá lọ látàárọ̀ yìí*
*Méjì lòún ṣẹ̀ṣẹ̀ rí*
*Àwòdì ló sì rí mẹ́jọ yìí*
*Ló wá ìyókù lọ*
*Ó kúkú le rí ju méjí lọ*
*Tóun sì ń wá mẹ́jọ  kún tòun*
*Ńgbà ó rí i pé Àwòdì pèyìndà tán*
*Ló bá padà wá inú ilé*
*Ló bá wáá kó tÀwòdì*
*Mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ*
*Ló bá kó o pọ̀ mọ́ tiẹ̀*

*Ó bá forí lé ọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmìlà*
*Ọ̀rúnmìlà ò sì mọ̀*
*Òun bá rúbọ fún Adìẹ*
*Wọ́n pèsè fún àwọn ayé*
*Ayé yẹ́ẹ́*
*Ó ní ó mọ́ọ́ lọ*
*Ó lÁdìẹ́ ó mọ́ọ́ bímọ́*
*Ire ọmọ fún Adìe lọ́pọ̀lọpọ̀*
*Ńgbà Àwòdì dé ilé*
*Ó kó méjì tó kù dé*
*Ẹ́bọ ò sì gbọ́dọ̀ kọ́já ọjọ́ náà*
*Àwòdì wọ́ ilé*
*Kò rí mẹ́jọ́ tó fi sílé mọ́*
*Taa ló ló òun lẹ́mọ́?*
*Ìbòòsí; oró ò*
*Ńgbà ó kébòòsí, kébòòsí*
*Tí ò rí ẹmọ mọ́*
*Tó ríi pé yóó jù*
*Ló bá kó méjì ọ̀hún tọ́ Ọ̀rúnmìlà lọ*
*Ọ̀rúnmìlà ní Adìẹ́ ti dé ìhín*
*'Adìẹ́ ti wáá rúbọ'*
*Àwòdì bá ró ó ńnú ara ẹ̀*
*Adìẹ́ ló kó ẹmọ́ òun méjọ́ tòun fiíel nùu*
*Àwòdì ní 'ẹmọ́ mélòó ló rú'?*
*Ọ̀rúnmìlà ní mẹ́wàá ni*
*Àwòdì ní 'Méjì péré ló rí tẹ́lẹ́ lòún fi wá ìyókù tòun lọ́'*
*Àṣé Adìẹ́ ló ja òun lólè*
*Ọ̀rúnmìlà ló dáa*
*Mọ́ọ́ fi méjì tiẹ́ tóo rí un náà rúbọ*
*Àwòdì bá rú méjì ọ̀hún*
*Àwòdì bá ń pa ọmọ méjì*
*Adìẹ́ ń pa mẹ́wàá*
*BÁdìẹ́ ò bá sì sọ́ra ẹ̀*
*Ńnúu mẹ́wàá tó bá pa*
*Bóyá lọ̀kan ó fì yè ńbẹ́*
*Èṣù ló ti kọ́ Àwòdì lágbọ́n*
*Ó ní ńnúu ọmọ́ mẹ́wàá tí Adìẹ́ bá pa*
*Ni o ti mọ́ọ́ mú soúnjẹ́*
*Torí òun ló ṣèrú*
*Básàá bá ti dé*
*Ní ó mọ́ọ́ pé 'N ò sẹ́bọ́ kọ̀ kọ̀ kọ̀ kọ̀ kọ́rọ́ńyín'*
*N ò sẹ́bọ́ kọ̀ kọ̀ kọ̀ kọ̀ kọ́rọ́ńyín*
*Àṣá ó balẹ́*
*Yóó gbé Ikàn ńnú ọmọ ẹ̀*
*Méjìi tÀṣá ní ń sọ́kọ́ Adìẹ́ tée dọ̀la*
*Kọ̀ kọ̀ kọ́rọ́ńyín*
*Awo adìẹ́ ló díá fún Adìẹ́*

*Adìe n fomi ojúú sògbérè ọmọ*
*Kọ̀ kọ̀ kọ́rọ́ńyín*
*Awo Àwòdì ló díá fún Àwòdì*
*Níjọ́ tí Àwòdì ń fomi ojú sògbére ọmọ*
*Wọ́n ní wọ́n ó sá káalẹ̀*
*Ẹbọ ọmọ ni kí wọ́n ó ṣe*
*Àwòdì nìkan ló gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Ló rúbọ*
*Adìẹ nǎà gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Ó rúbọ*
*Adìẹ ni ò ṣeun*
*Adìẹ ni ò sèèyàn*
*Ó lóun ò ṣebọ kọ̀ kọ̀ kọ́rọ́ńyín*

***Òtúá Ọ̀sá A***
*Ifá desea bien a esta persona: Él lo manda no romper ningún juramento. Ifá ve a dos personas que están en necesidad de niños. Ellos dos deben realizar sacrificio en el sitio donde este Ifá se lanza. Ellos dos tendrían niños. Ellos deben sacrificar dos ratas en el cruce.*

*Kò kò kórónyín*
*El Babaláwo de la Gallina lanza adivinación para la Gallina*
*En el día que ella estaba llorando debido a los niños*
*Ellos le dijeron que ella tendría muchos niños*
*Ellos le dijeron que realizara sacrificio para los niños*
*Kò kò kórónyín*
*El Babaláwo del Águila lanza adivinación para el Águila*
*El Águila también estaba llorando debido a los niños*
*Ellos dijeron al Águila que ella tendría muchos niños también*
*Pero debe realizar sacrificio para los niños*
*Los dos habían ido juntos a Òrúnmìlà*
*' Pueda nosotros dos tener niños '? Ellos dos habían preguntado a Òrúnmìlà*
*' Ustedes dos tendrían niños ' Òrúnmìlà dijo*
*Él les pidió que sacrificaran diez ratas cada uno*
*Y también al sacrificio mucho dinero en diez partes cada uno*
*Él dijo a ellos dos tendrían muchos niños en tierra*
*Ellos regresaron a sus casas*
*La Gallina fue después en buscar de las ratas*
*Ella vio dos*
*Ella guardó los dos*
*Cuando - el Águila volvió de su propia aventura*
*Ella vio ocho*
*La Gallina empezó pensando entonces ' hoy es la fecha limite para nuestro sacrificio*
*' Este hombre dijo que nosotros debemos traer las ratas hoy '*
*' Y yo no he podido conseguir estas ratas*
*' Yo he podido conseguir sólo dos '*
*' Pero aquí esta el Águila que ha visto ocho '*

*' Él incluso había ido buscando las dos restantes '*
*¿' Él podría igualarse muchos más de dos '?*
*' Aquí yo estoy buscando ocho '*
*Cuando ella notó que el Águila había salido para la búsqueda de más ratas*
*Ella entró en el cuarto del Águila*
*Ella robó las unas que pertenece al Águila*
*Todas los ocho*
*Ella lo empaco como suyo*
*Y llevo todo a Òrúnmìlà*
*Pero desde que Òrúnmìlà no supo*
*Él uso a preparar el sacrificio para la Gallina*
*Él ofreció el sacrificio para las brujas*
*La vida agradó la Gallina*
*Òrúnmìlà le pidió que fuera*
*Él dijo a la Gallina que ella tendría niños de aquí en adelante*
*' Pueda la fortuna buena de niños está con usted la Gallina en abundancia ' Òrúnmìlà oro*
*Cuando el Águila llegó a casa*
*Ella había encontrado las restantes dos ratas*
*Para pegar la fecha limite*
*El Águila fue a verificar el lugar que ella guardó las ratas restantes*
*Ella no podría encontrar los ocho de nuevo*
*¿Quién podría robar estas ratas?*
*Ìbòòsí; oró ò*
*Después de gritar y llorar por ayuda para llevar a la recuperación de las ratas robadas*
*Ella no tuvo éxito*
*Ella notó que sería tarde si ella no hace algo inmediatamente*
*Ella tomó las dos que ella encontró después a Òrúnmìlà*
*' La Gallina había estado aquí ' Òrúnmìlà dijo alegremente*
*' Ella había estado aquí para realizar el sacrificio '*
*Asombrado, el Águila lloró interiormente*
*' Debe ser la Gallina que robó mis ratas ' Ella razonó rápidamente*
*' Cuántas ratas ofreció ella '? Ella preguntó Òrúnmìlà*
*' Ella ofreció diez ' Òrúnmìlà contesto roncamente*
*' Pero ella tenía sólo dos como en el momento yo fui pareciendo para el resto mío propio '*
*El Águila dijo*
*' Así que era la Gallina que robó mis ratas ' ella dijo a Òrúnmìlà*
*' No importa ' Òrúnmìlà dijo*
*' Use las dos usted que tiene como sacrificio '*
*Eso era cómo el Águila sacrificó las dos ratas*
*El Águila desde entonces en adelante empezó a incubar dos huevos*
*La Gallina incubaría diez o más aun*
*Pero si la Gallina no tiene cuidado*
*Fuera de los diez incubados por la Gallina*
*Apenas habría que uno sobrevive fuera del lote*
*Es Èsù que había enseñado el Águila*
*' Fuera de los niños incubados por la Gallina '*
*' Usted debe escoger algunos como comida para usted '*

*' Desde que ella es la que tocó falta ' Èsù dijo*
*Una vez el Águila vuela encima de una área donde una Gallina está yendo con sus polluelos*
*Ella empezaría a bravear ' yo no realicé el sacrificio de ' kò kò kò kórónyín '*
*Yo no realicé el sacrificio de ' kò kò kò kòrònyín '*
*El Águila entraría un deslizamiento rápido*
*Y escoge uno de los polluelos*
*Los dos incubados por el Águila el primer día son una preocupación de la Gallina hasta la fecha*
*Kò kò kórónyín*
*El Babaláwo de la Gallina lanza adivinación para la Gallina*
*En el día que ella estaba llorando debido a los niños*
*Kò kò kórónyín*
*El Babaláwo del Águila lanza adivinación para el Águila*
*El Águila también estaba llorando debido a los niños*
*Le pidieron que cuidara de la tierra*
*Y realiza el sacrificio para los niños*
*Es sólo el Águila que oyó hablar del sacrificio*
*Y lo realiza con verdad*
*La Gallina también realizó el sacrificio*
*Pero ella lo hizo falsamente*
*La Gallina es el que no es humano*
*Ella confesó para no haber realizado el sacrificio Kò kò kórónyín*

***Òtúá Ọ̀sá B***
*Ifá pé kí eléyìun ó rúbọ, òun ò níí jẹ́ ó réèmọ̀ọ́ kín nìí. Eléyìun ò gbọ́dọ̀ dá hẹ̀ẹ̀ ẹni tí ń sawo o.*
*Ọ̀bábambá*
*Ọ̀mọ́mọ́ǹmọ́*
*Ọ̀rọ̀ bẹ́ǹìkàn mọ́ yọ̀rọ̀ bí ẹni ti ò tiẹ̀ gbọ́n*
*A díá fún Wínnláwẹ̀ Obìnrin Àjàgùnmọ̀lè*
*Wínláwẹ̀ Obìnrin Àjàgùnmọ̀lè ló jí ní kùtùkùtù òwúrọ̀*
*Ní wá ń fomi ojú sògbérè ọmọ*
*Ńgbà ti í bìí*
*Ọ́ bí Agbe fún Ojolú*
*Ńgbà ti ó bìí*
*Ọ́ bí Àlùkò Dòdòòdò fún Ojosùn*
*Ńgbà ti ó tùún bí*
*Ó bí Odídẹ́rẹ́ fún Olúwo*
*Ọmọ atọ̀run gbégbá ajé karí wáyé*
*Ńgbà ti ó bìí*
*Ọ́ bí Àwòdì fún Olúkàro Àsá*
*Ńgbà ó pẹ́*
*Agbe dàgbà*
*Wọ́n tẹ̀fá fún Agbe*
*Wọ́n tẹ̀fá Àlùkò*
*Wọ́n tẹ̀fá fún Odídẹ́rẹ́ mòfé*

*Àwòdì lò dÌkàrò*
*Kèè tíì tẹfá*
*Ló bá sawo lọ sílé Olókun*
*Ó dé ilé Olókun tán*
*Ọlókun gbà á láàyè*
*Ńgbà ó pẹ́*
*Wọ́n ráńṣẹ́ sí Àwòdì àwọn ò gbúròó ẹ̀*
*Wọ́n ní Àwòdì ń bẹ nílé Olókun*
*Ń bẹ ńbẹ̀ tí ń sawo*
*Wọ́n lÁwòdì?*
*Àwòdì tí è tíì tẹfá*
*Ló dÌkàrò lásán ní ń sawo?*
*Wọ́n bá kèjàsì*
*Wọ́n ní ò dúó wọgbódù tí fí ń sawo ò o ò*
*Àwòdì ò mọ̀ dúó wọgbódù tí fí ń sawo ò ò ò*
*Àwòdì ò mọ̀ dúó wọgbódù tí fí ń sawo*
*Àwòdì ò mọ̀ dúó wọgbódù tí fí ń sawo o o o*
*Wọ́n bá rán Agbe pé ó lọ̀ọ́ pè é wá*
*Agbe bá dọ́hùún*
*Ó ní 'ńbo lÀwòdí wà'*
*Wọ́n ní ń be nígbódù*
*Tí ń sawo*
*Tí ń tẹ̀ wọ́n nÍfá*
*Ńgbàa Agbe dé ẹnu ọ̀nà Igbó Odù*
*Lòun náà kèjàsì*
*Ó lẹ́ẹ́kú o ò ọmọ Àgbọnnìrègún gbogbo Babaláwo*
*Wọ́n ní Hin*
*Ọ̀bábámbá, Ọ̀mọ́mọ́ǹmọ́, Ọ̀rọ̀ bẹ́nòkàn mọ yọ̀rọ̀ bí eni ti ò tiẹ̀ gbọ́n*
*Hin*
*A díá fún Wínnláwẹ̀ Obìnrin Àjàgùnmọ̀lè o*
*Hin*
*Níjọ́ tí ń fomi ojú sògbérè ọmọ*
*Hin*
*Ó bí Agbe fún Ojolú*
*Hin*
*Ó bí Àlùkò Dòdòòdò fún Ojosùn*
*Hin*
*Ó bí Odídẹrẹ́ fún Olúwòó, ọmọ atọ̀run gbégbá aje karí wáyé*
*Hin*
*Ó bí Àwòdì fún Olúkarò Àṣá*
*Hin*
*Wọ́n tẹfá fún  Agbe*
*Hin*
*Wọ́n tẹfá fún Àlùkò*
*Hin*
*Wọ́n tẹfá fún Odídẹrẹ́ mòfé*
*Hin*

*Àwòdì lò dÌkàrò ni ò dúó tẹfá tí fí  n sawo*
*Hin*
*ó ní tí fí ń sawo ò o ò o*
*Àwòdì ò mọ́ dúó wọ gbódù ti fí ń́ sawo ò ò ò*
*Àwòdì ò mọ̀mọ̀ dúó wọgbódù tí fí ń́ sawo o o o*
*Àwòdì ò mòmò dúó wogbódù tí fí ń sawo*
*Àwòdì ò mọ̀mọ̀ dúó wogbódù tí fí ń sawo o o o*
*Àwòdì gbọ́ nnú igbó ìgbàlẹ̀*
*Ó bá yọjú sí I*
*Agbe ní 'ńjóo nìwọ́ tẹ́fá'*
*Àwòdì bá fÀsẹ̀ ba ẹnu ẹ̀*
*Ló bá ta Agbe láṣẹ*
*Agbe bá kọrí sínú igbó*
*Ńgbà ti ọ́n dúó ti wọn ò rí Agbe*
*Wọ́n bá tún rán Àlùkò*
*'Ńgbà táà rí Agbe'*
*'O ò yáa lọ́ọ́ pe Àwòdì ọ̀hún wá'?*
*Àlùkò tún dé ẹnu ọ̀nà ilé Olókun*
*Ó ní ńbo lÀwòdí wà?*
*Wọ́n tún ní ń bẹ nÍgbódù*
*Tí ń tẹ̀ wọ́n nÍfá*
*Òun náà kèjàsì*
*Ó lẹ́ẹ́kù ò ọmọ Àgbọnnìrègún gbogbo Babaláwo*
*Wọ́n ní him*
*Ọ̀bábámbá. Ọ̀mọ́mọ́ǹmọ́. Ọ̀rọ̀ bẹ́nìkan mọ yọ̀yọ̀ bí ẹni ti ò tiẹ̀ gbọ́n*
*Hin*
*Díá fún Wínnláwẹ̀ Obìnrin Àjàgùnmọ̀lè o*
*Hin*
*Níjọ́ ti ń fomi ojú sògbérè ọmọ*
*Hin*
*Ó bí Agbe fún Ojolú*
*Hin*
*Ó bí Àlùkò Dòdòòdò fún Ojosùn*
*Hin*
*Ó bí Odídẹ́rẹ́ fún Olúwo, ọmọ atọ̀run gbégbá ajé karí wáyé*
*Hin*
*Ó bí Àwòdì fún Olúkàro Àṣá*
*Hin*
*Wọ́n tẹfa fún Agbe*
*Hin*
*Wọ́n tẹfá fún Àlùkò*
*Hin*
*Wọ́n tẹfá fun Odídẹ́rẹ́ mòfé*
*Hin*
*Àwòdì ló dÌkàrò kò mọ̀mọ̀ dúó wọ gbódù tí fí  ń́ sawo*
*Àwòdì ò mo dúó wọ gbódù tí fí ń́ sawo ò ò ò*
*Àwòdì ò mọ̀mọ̀ duó wọ gbódù tí fí ń sawo o o o*

*Àwòdì ò mọ̀mọ̀ dúó wọ̀gbódù ti fí n sawo o o o*
*Àwòdì tún gbọ́*
*Ó kàṣẹ bọnu*
*Ó ta Àlùkò náà lÁṣẹ*
*Ó ní kóun náà ó mọ́ọ lọ*
*Wọ́n bá rán Odídẹ̀ẹ́ mòfé*
*Pé kóun náà ó lọ́ọ́ pe Àwòdì wá*
*Òun niṣẹ́ kàn.*
*Odídẹ̀ẹ́ bá tọ àwọn 'Bó bá gbóná kèé jó ni'*
*Àwọn 'Ìkọ̀ òwú è é rọ̀jà ó mọ́ bọ̀'*
*Àwọn 'Ìta werere nàá la sì dé'*
*Àwọn 'Bàlà ni kóóse'*
*Ẹ̀ gbàmí*
*Wọ́n ti rán Agbe níṣẹ yìí*
*Wọ́n ti rán Aluko náà*
*Wọ́n níwọ Odídẹ̀ẹ́*
*Wọ́n ní pẹ̀lẹ́ pẹ̀lẹ́ ni o fi jíṣẹ̀ o*
*Mọ́ pèé kò gbọ́n o*
*Mọ́ pèé kò mọ nǹkankaán ṣe*
*Mọ́ sọ̀rọ̀ ti ó bi nínú o*
*Bóun náà ti dọ́hùún*
*Ńbo lÀwòdí wà?*
*Wọ́n ní ń bẹ̀ nígbódù*
*Ti gbé ń sawo*
*Bó ti yọ sọ́hùún*
*Ní ń pé baba ǹlẹ́ o*
*Ẹ̀là bọ rú*
*Ẹ̀là bọ yè*
*Ẹ̀là bọ ṣíṣẹ̀*
*Ní bá ń yíràá*
*Àwòdí wèyìn ló rí Odídẹ̀ẹ́*
*Ní ń fẹ̀nunú yílẹ̀*
*Àwòdí ló tó!*
*Àwòdí ní àwọn ọ̀gá òun nìí*
*Ìkó ti sì ń bẹ̀ níḋìí Odídẹ̀ẹ́ lónìí*
*Ìdí Àwòdì ni Olókun ti sán an mọ́ tẹ́lẹ̀*
*Àṣá bá mú Ìkó ọ̀hún*
*Ló bá sán an mọ́ Odídẹ̀ẹ́ níḋìí*
*Àwòdì ní táa bá rán ni níṣẹ́ ẹ̀rú*
*Tọmọ làá fíí jẹ́ ẹ*
*Bi ti ń bẹ́ẹ̀ toríi rẹ̀ ń wú*
*LOdídẹ̀ẹ́ bá rora ń pé*
*Kóun ó mú ọ délé*
*Ìkọ́ òwú è é rọ̀jà ó mọ́ bọ̀*
*Kóun ó mú ọ délé ni*
*Èrò wọ́ọ́rọ́ ni tòòrí*
*Kóun ó mú ọ délé ni o*

*Ìta werere náà la sì dé*
*Kóun ó mú ọ délé o*
*Kínúù rẹ́ ó rọ̀ o*
*Àwòdì bá tẹ̀lé Odídẹ́rẹ́ relé*
*Àwọn Àpáǹkóló Awo sì ju Awo lo ¸*
*Ọ̀rúnmìlà bá wọ inú ilé*
*Ó ní Agbe táwọn rán sí ọ*
*Àwọn ò rí I mọ́*
*Àlùkò táwọn rán sí ọ*
*Àwọn ò rí I mọ́*
*Ọ̀rúnmìlà bá na àṣẹ sí àwòdì*
*Ló bá gbé Àwòdì mì*
*Wọ́n ní Àpàǹkóló ò*
*Awó mọ̀ jAwo lo¸*
*Awo gbáwo mì torí torí*
*Àpáǹkóló o ò ó*
*Awó mò jAwo lo¸*
*Awo gbáwo mì tIfá tIfá.*

***Òtúá Ọ̀sá B***
*Ifá le pide a esta persona que realice sacrificio. Ifá dice que él no le permitiría ver un suceso (casualidad, ocurrencia, incidente) malo. Le aconsejan que no relegue el orden de sacerdocio de Babaláwos.*

*Òbábámbá*
*Òmómónmó*
*Òrò bénìkàn mó yòrò bí eni tí ò tiè gbón*
*Adivinación lanzada para Wínnláwè el pariente de Àjàgùnmòlè*
*Wínnláwè, el pariente de Àjàgùnmòlè se despertó temprano por la mañana un día*
*Ella estaba llorando debido a los niños*
*La primera vez ella tenía un bebé*
*Ella dio nacimiento a un bebe Agbe para Ojolú*
*La próxima vez ella tenía un bebé*
*Ella tenía Àlùkò Dòdòòdò fún Ojosùn*
*La tercera vez ella tenía un bebé*
*Ella tenía Odíderé para Olúwòó*
*El niño de Atòrun gbégbá ajé karí wáyé*
*La próxima vez ella tenía un bebé*
*Ella tenía Àwòdì para Olúkàro Àsá*
*Después de un tiempo largo*
*Agbe envejeció bastante a un adulto*
*Ellos iniciaron a Agbe en el culto de Ifá*
*Ellos también comenzaron Àlùkò en Ifá*
*Ellos también comenzaron Odíderé mòfé en el culto de Ifá*
*Àwòdì se volvió sin embargo un, Ìkàrò*
*Él no se había consagrado en Ifá*
*Él aventuró sacerdocio a la casa de Olókun*

*Él llegó la casa de Olókun*
*Olókun le permitió practicar su Ifá*
*Después de un tiempo largo*
*Ellos enviaron por Àwòdì cuando ellos no pudieran oír hablar de él*
*' Àwòdì está en la casa de Olókun', vino la contestación*
*' Él está allí practicando su Ifá'*
*¡' Àwòdì'!!!*
*¿No se ha introducido eso en el culto de Ifá '?*
*¿Se volvió él un Ìkàrò ordinario y empezó practicando?*
*Ellos todos en unísono reventaron en la canción de Ìjàsì*
*Él no esperó entrar en el sagrado bosque de Ifá antes de practicar*
*Àwòdì no espero entrar en el sagrado bosque de Ifá antes de practicar*
*Àwòdì no espero entrar en el sagrado bosque de Ifá antes de practicar*
*Àwòdì no espero entrar en el sagrado bosque de Ifá antes de practicar*
*Ellos concluyeron para enviarle a Agbe ir y llamarlo*
*Agbe llegó a la casa de Olókun*
*' Dónde esta Àwòdì '? Él preguntó*
*' Él está en el sagrado bosque de Ifá' que Ellos dijeron*
*' Él está allí practicando '*
*' Y también inicio a las personas en el culto de Ifá'*
*Agbe sin retraso fue a la entrada del bosque*
*Él también reventó en Ìjàsì*
*Él dijo que yo lo saludo todos los niños de el Àgbonnìrègún todos los Babaláwo*
*Ellos respondieron, Hin*
*Óbábámbá, Òmómónmó, Òrò bénìkàn mo yòrò bí eni tí ò tiè gbón*
*Hin*
*Adivinación del lanzamiento para Wínnláwè el pariente de Àjàgùnmòlè*
*Hin*
*En el día ella estaba llorando debido a los niños*
*Hin*
*Ella dio nacimiento al bebe al enemigo de Agbe Ojolú*
*Hin*
*Ella tenía Àlùkò Dòdòòdò para Ojosùn*
*Hin*
*Ella tenía Odíderé para Olíwòo, el niño de Atòrun gbégbá ajé karí wáyé,*
*Hin*
*Ella tenía Àwòdì para Olúkarò Àsá*
*Hin*
*Ellos iniciaron a Agbe en el culto de Ifá*
*Hin*
*Ellos iniciaron a Àlùkò en el culto de Ifá*
*Hin*
*Ellos también iniciaron Odíderé mòfé en el culto*
*Hin*
*Àwòdì se volvio un Ìkàrò y no espero por la iniciación antes de practicar*
*Hin*
*Antes de que él empiece practicando*

*Àwòdì no espero ser consagrado un Babaláwo antes de que él empezara practicando*
*Àwòdì no espero ser consagrado un Babaláwo antes de que él empezara practicando*
*Àwòdì no espero ser consagrado un Babaláwo antes de que él empezara practicando*
*Àwòdì no espero ser consagrado un Babaláwo antes de que él empezara practicando*
*Àwòdì oyó esto dentro del sagrado bosque*
*Él salió para ver a la persona que está perturbándolo*
*¿Con enojo Agbe dijo, ' Cuándo fue iniciado usted '?*
*Àwòdì con molestia puso su Àse en su boca*
*Él maldijo Agbe*
*Agbe se dirigió hacia el bosque salvaje en lugar de casa*
*Después de esperar sin ver Agbe*
*Ellos enviaron Àlùkò*
*' Cuando nosotros no pudiéramos ver Agbe'*
*' Hábría no ser usted para ir Àwòdì de la llamada por nosotros ' los superiores dijeron*
*Àlùkò también llego a la puerta de Olókun*
*¿Preguntó él también bastante enojadamente ' Dónde esta Àwòdì'?*
*Ellos también lo contestaron ' En el sagrado bosque '*
*' Él está allí comenzando a las personas en el culto de Ifá'*
*A la entrada él reventó también en Ìjàsì*
*Yo lo saludo todos los niños de Àgbonnìrègún todo los Babaláwo*
*Hin*
*Òbábámbá, Òmómónmó, Òrò bénìkan mo yòrò bí eni tí ò tiè gbón*
*Hin*
*Adivinación del lanzamiento para Wínnláwè el pariente de Àjàgùnmòlè*
*Hin*
*En el día ella estaba llorando debido a los niños*
*Hin*
*Ella dio nacimiento al bebe Agbe para Ojolú*
*Hin*
*Ella tenía Àlùkò para Ojosùn*
*Hin*
*Ella tenía Odídere para Olúwòó, el niño de atòrun gbégbá ajé karí wáyé,*
*Hin*
*Ella tenía Àwòdì para Olúkàro Àsá*
*Hin*
*Ellos iniciaron Agbe en el culto de Ifá*
*Hin*
*Ellos iniciaron Àlùkò en el culto de Ifá*
*Hin*
*Ellos también iniciaron Odíderé mòfé en el culto*
*Hin*
*Àwòdì se volvió un Ìkàrò y no espero por la iniciación antes de practicar*
*Àwòdì no espero ser consagrado un Babaláwo antes de que él empezara practicando*
*Àwòdì no espero ser consagrado un Babaláwo antes de que él empezara practicando*
*Àwòdì no espero ser consagrado un Babaláwo antes de que él empezara practicando*
*Àwòdì oyó esto de nuevo*
*Él pone su Àse' en su boca*

*Y maldijo, Àlùkò-Dòdòòdò con esto*
*Él le ordenó que vagara sin designio*
*Los superiores como un último recurso le preguntaron a Odíderé mòfé*
*' Ese es su vuelva a ir y encontrar Àwòdì y tráigalo aquí '*
*' Usted es el próximo en la lista de mandado '*
*Odíderé fue a consultar a los sacerdotes entonces ' Bó bá gbóná kèé jó ni '*
*Los sacerdotes 'Ìkó òwú è é rojà ó mó bò '*
*Los sacerdotes ' Ìta werere náà la sì dé '*
*Los sacerdotes ' Bàlà ni náà kóóse '*
*' Por favor ayúdeme ' Él rogó*
*' Ellos han enviado Agbe en este mandado '*
*' Ellos también han enviado Àlùkò en el mismo mandado '*
*' Usted Odíderé' que Ellos llamaron*
*' Usted debe usar su frialdad a entregar este mensaje '*
*' Nunca diga él no es bastante hábil '*
*' Nunca diga él no es sabio '*
*' No dice nada que lo enfurecería ' ellos advirtieron*
*Inmediatamente él llegó allí*
*Donde es Àwòdì fue su primera pregunta*
*Él está en el sagrado bosque*
*Él está allí practicando su Ifá*
*En ver el bosque*
*Él de lejos empezó a saludar ' yo lo saludo Baba '*
*Èlà bo rú*
*Èlà bo yè*
*Èlà bo síse*
*Él postró*
*Àwòdì miro atrás y vieron Odíderé*
*Doblando la rodilla y arqueando con su boca que toca la tierra*
*' Eso es bastante ', Àwòdì dijo*
*Él es uno de mis mentores, Àwòdì dijo*
*Las plumas rojas a la cola de Odíderé*
*Olókun lo había envuelto al principio a la cola de Àwòdì*
*Àwòdì tomo el manojo entero de las plumas rojas*
*Y los apiló a la cola de Odíderé*
*' Si uno se envía en un mandado con voz baja implicativa ' dijo Àwòdì*
*' Uno debe usar su sentido especial para entregarlo para escapar al castigo culpable '*
*Cuando Àwòdì estaba diciendo esto, sintiéndose en serio exaltados por el gesto de Odíderé*
*Silenciosamente y metódicamente, Odíderé cortó en algunas palabras*
*' Yo debo ir con usted '*
*' Ìkó-ówú nunca iría al mercado sin volver '*
*' Yo debo ir con usted '*
*' Está sin fricción unte la manteca-nuez (sheanut) '*
*' Yo debo ir con usted '*
*' Nosotros somos justos en alrededor de la ciudad de Ìta era '*
*' Yo debo ir con usted '*
*' Usted debe pacificarse '*

*Àwòdì por estar acariciando llegaron casa con Odìderè*
*El Àpánkólós Babaláwos es mejor apreciado que el otro*
*Òrúnmìlà entro en la casa*
*' Agbe que nosotros enviamos a usted ' Òrúnmìlà dijo*
*' Nosotros no podríamos verlo de nuevo '*
*' Àlùkò que nosotros también enviamos a usted '*
*' Nosotros tampoco podríamos verlo '*
*Òrúnmìlà apunto su propio Àse a Àwòdì*
*Él tragó Àwòdì completamente*
*Ellos todos cantaron en unísono con miedo ' Apánkóló'*
*Sacerdote es mejor apreciado que el otro es*
*Un sacerdote ha tragado a simplemente otro sacerdote de la cabeza al dedo del pie*
*Àpánkóló, ellos cantaron*
*Sacerdotes son mejores apreciados que otro es*
*Un sacerdote superior había tragado a otro sacerdote con su Ifá.*

*Òtúá Ìká A*
*Iré ọmọ fún eléyìun. Ayé ó ye, é, yóó sì nísinmi. Ifá pé ká rúbo, è, kó pé dáadáa.*

*Ó túká wááráwá*
*Ó dàálẹ waarawa*
*Ẹ̀rìgì Awo Àgbasà*
*A díá fún wọn ńIsẹ̀ṣẹ à á kéré*
*Níbi wọ́n gbé ń fohun ẹbọ́ rúbọ*
*Wọ́n kí wọ́n ó rúbọ*
*Wọ́n láyé ó ye, wọ́n*
*Wọ́n lọ́kàan wọ́n ó balẹ*
*Wọ́n ó sì nísinmi*
*Ṣùgbọ́n kí wọ́n ó rúbọ*
*Wọ́n bá rúbọ*
*Wọ́n rúbọ tan ni gbogbo ẹ bá dáa*
*Wọ́n ló túká wááráwá*
*Ó dàálẹ waarawa*
*Ẹ̀rìgì Awo Àgbasà*
*A díá fún wọn ńIsẹ̀ṣẹ à á kéré*
*Nibi wọ́n gbé ń fohun ẹbọ́ rúbọ*
*Owó la fí ń rúbọ nílẹ*
*Jẹ́ ó fín Ifá*
*Ẹrigí Awo Àgbasà*
*Ọba aládé a róhun , ebọ*
*Àgbàdo ti ń bẹ nílẹ yí*
*Ohun ẹbọ níí ṣe*
*Ẹrigí Awo Àgbasà*
*Ọba aládé a róhun , ebọ*
*Òkòkó, Àkùko,*
*Méjèéjì ti ń bẹ ńlè yí*
*Ohun ẹbọ níí ṣe*

*Ẹrigí Awo Àgbaà*
*Ọba aládé a róhun ẹbọ*
*Ẹyẹlé ti ń bẹ ńlẹ̀ yîì Ifá*
*Ohun ẹbọ níí ṣe*
*Ẹrigí Awo Àgbasà*
*Ọba aládé a róhun ẹbọ*
*Ewúrẹ́ ti ń bẹ ńlè yìí*
*Ohun ẹbọ níí ṣe*
*Ẹrigí Awo Àgbasà*
*Ọba aládé a róhun ẹbọ*
*Àgùtàn bọ̀lòjọ̀ ti ń bẹ ńlẹ̀ yìí*
*Ohun ẹbọ níí ṣe*
*Ẹrigí Awo Àgbasà*
*Ọba aládé a róhun ẹbọ*
*A rúbọ ó pé*
*A bímọ nígbà yí ò a bímọ*
*Ẹrigí Awo Àgbasà*
*Kín la fi ń pọnmọ gírí?*
*Kíjìpá lèèmù leemu*
*Táa fi rúbọ ní ń bẹ ńlẹ̀ yìí*
*Ká mọ́ọ gbọ́mọ jó*
*Ẹ̀rigí Awo Àgbasà*
*Ọba aládé a róhun ẹbọ.*

***Òtúá Ìká A***
*Ifá desea bien a esta persona. La vida lo agradaría y él tendría descanso. Ifá le implora que sacrifique por completo. Le desean la fortuna de niños.*

*Disuelve (deshacer, desaparecer) prontamente*
*Vierte abajo sin el impedimento*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbasà*
*Adivinación lanzada para ellos a Ìsèse à á kéré*
*Donde ellos estaban usando los objetos sacrificatorios apropiados como ofertorio*
*Les pidieron que realizaran sacrificio*
*Esa vida los agradaría (complacería, gustaría)*
*Que ellos tendrían descanso de mente*
*Y que ellos también tendrían paz*
*Pero ellos deben ofrecer su sacrificio prescrito*
*Ellos terminaron la ofrenda del sacrificio y todo se puso bueno para ellos*
*Ellos dijeron que disuelve prontamente*
*Vierte abajo sin el impedimento*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbasà*
*Adivinación lanzada para ellos a Ìsèse à á kéré*
*Donde ellos estaban usando los objetos sacrificatorios apropiados como ofertorio*
*Es dinero que nosotros usamos en el sacrificio*
*Ifá le permitió demostrar eficacia*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbasà*

*El rey coronado, nosotros hemos visto los objetos de sacrificio*
*El maíz que nosotros hemos proporcionado aquí en la tierra*
*Es un objeto de sacrificio*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbàsà*
*El rey coronado, nosotros hemos visto los objetos de sacrificio*
*La gallina y el gallo*
*Los dos que nosotros hemos proporcionado aquí en la tierra*
*Ellos son objetos de sacrificio*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbàsà*
*El rey coronado, nosotros hemos visto los objetos de sacrificio*
*La paloma que nosotros hemos proporcionado aquí en la tierra*
*Es un objeto de sacrificio*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbàsà*
*El rey coronado, nosotros hemos visto los objetos de sacrificio*
*La cabra que nosotros hemos proporcionado aquí en la tierra*
*Es un objeto de sacrificio*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbàsà*
*El rey coronado, nosotros hemos visto los objetos de sacrificio*
*La oveja bonita que nosotros hemos proporcionado aquí en la tierra*
*Es un objeto de sacrificio*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbàsà*
*El rey coronado, nosotros hemos visto los objetos de sacrificio*
*Nosotros ofrecimos nuestro sacrificio y está lleno*
*Nosotros damos ahora de aquí en adelante el nacimiento a los bebés*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbàsà*
*¿En qué nosotros usamos atando al bebé?*
*The thick, kijipa (kíjìpá: un tipo anticuado de tela llevado por los Yorubas. es tan espeso como el tarpaulin. Usado, para prevenir el frío pero también una tela que demuestra la afluencia)*
*El que nosotros hemos usado como el sacrificio está aquí en la tierra*
*Permítanos abrazar a los niños juntos*
*Èrìgì el sacerdote de Àgbàsà*
*El rey coronado, nosotros hemos visto los objetos de sacrificio.*

***Òtúá Ìká B***
*Ifá pé kí eléyìun ó rúbọ torí ọ̀nà ajé kan ó sìí fún un. Ifá pé kó mọ́ọ fi díẹ̀díẹ̀ kún ọjà ti ń tà torí àwọn ẹ̀èyàn ó móo ṣẹ̀ṇìní è. Ifá tó jé kí àwon ẹaláròóbò ọ́ móo jẹ̀rè nìí.*

*Ó túká wááráwá*
*Ó dalẹ waarawa*
*Ẹ̀rìgì Awo Àgbasà*
*A díá fún Aláròóbọ̀*
*Tòun tèké*
*Tòun tàyọnusọ*
*Tòun àtọ̀rọ̀ àràmọ̀ndà létè*
*Níjọ́ọ wọ́n ń sunkún àwọn ò lájé lọ́wọ́*

*Àwọ́n le lájé báyìí?*
*Nígbà ìwásẹ̀*
*BÁláròóbọ̀ bá ra nǹkan ní ọ̀kẹ́ kan*
*Ọ̀kẹ́ kan nàá ní ọ́n tíí tà á*
*Nígbà àwọn òǹràjà bá dé*
*Ọ̀nà ti wọ́n ó gbèé rà á*
*Ti ó fi dín ní ọ̀kẹ́ kan ni wọ́n ó mọ́ọ̀ sán*
*Ọ̀nà ti ọ́n sì ti ń lọ́ọ́ gbé nǹkan wá sì nìí*
*Ó jìnnà pupọ*
*Ló bá tọ Ọ̀rúnmìlà lọ*
*'Ìwọ tóòó mọ́ọ̀ lọ ọ̀nà tó jìnnà'*
*'Tóòó mọ́ọ̀ ra nǹkan wá fún wa'*
*'Àwọn èèyàn tìí ò mọ̀ ṣẹ̀ ẹ̀'*
*'Bóo bá rajà ní ọ̀kẹ́ kan'*
*'Mọ́ọ̀ pè é ní ọ̀kẹ́ kan àbọ̀'*
*'Kó lè baà pé ọ'*
*'Kó o lè baà loòmíìn'*
*'Kó ó tóó jẹ'*
*'Kó ó tóó mu'*
*Ni Aláròóbọ̀ ń ṣe tée dòní*
*N tÍfá wí fún ọn nàá ni ọ́n ń lò*
*N ní wá ń jó ní wá ń yọ̀*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní bẹ́ẹ̀ làwọn Babaláwo tòún wí*
*Ó túká wááráwá*
*Ó dàálẹ̀ waarawa*
*Ẹ̀rìgì Awo Àgbasà*
*A díá fún Aláròóbọ̀*
*Tòun tèké*
*Tòun tàyọnusọ*
*Tòun àtọ̀rọ̀ àràmọ̀ǹdà létè*
*Níjọ́ọ̀ wọ́n ń sunkún àwọn ò lájé lọ́wọ́*
*Ẹbọ ajé ni ọ́n ní wọ́n ó ṣe*
*Wọ́n gbẹ́bọ ńbẹ̀*
*Wọ́n rúbo*
*Rírú ẹbọ*
*Èèrù àtùkèsù*
*Ajé wáá jẹ dẹ́kùlée wa*
*Wìnnìwìnnì*

***Òtúá Ìká B***
*Ifá le pide a esta persona que realice el sacrificio porque una puerta de riqueza se abriría para él. Ifá le aconseja que agregue un poco el margen de ganancia a sus mercancías porque él debe ganar más dinero de sus ventas. Éste es el verso que les enseña a intermediarios a agregar las ganancias.*

*Disuelve prontamente*
*Vierte abajo sin un tirón (enganche)*
*Èrigì el sacerdote de Àgbàsà*
*Adivinación lanzada para las mujeres del Mercado*
*Con su engaño*
